Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras
São Francisco do Conde (BA) | vol. 5, nº Especial I | p. 140-153 | jan./ jun.2025.

# Ọgbọ́n ìṣẹ̀dá àti àwòmọ́ afọ̀: ìlànà fún ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá

# Sabedoria natural e o olhar de quem vê: um guia para analisar a literatura oral iorubá

**Adewale Lukman ADEMUYIWA Ph.D.** *
https://orcid.org/0009-0004-8977-4957

**ÀṢAMỌ̀**
Láti ibi ète ìṣẹ̀dá ni ìbẹ̀rẹ̀ ìgbéjáde ẹ̀yà lítíréṣọ̀ yòówù ti máa ń wáyé, èyí sì máa ń gba ìrònújinlẹ̀ àti ọgbọ́n àtinúdá oníṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀. Nígbà tí ìṣẹ̀dá lítíréṣọ̀ bá kalẹ̀ tán, ó ni àwọn àbùdá àti àwòmọ́ afọ̀ kan tí oníṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ gbọdọ̀ dì mẹ́rù nínú ìgbéjáde ìpohùn tàbí ìṣèré rẹ̀. Ìdí ni pé àwọn àwòmọ́ afọ̀ yìí ni wọ́n máa ń jẹ́ àwòmọ́ ìdájọ́, èyí tí àwọn òǹwòran tàbí òǹgbọ́ máa ń lò gẹ̀gẹ̀ bí òṣùwọn tàbí òté láti ṣe ìdájọ́ irúfẹ́ ẹ̀yà ìpohùn kan tàbí apohùn kan pàtó. Onírúurú ète tí àwọn apohùn ń lò fún ìṣẹ̀dá ìpohùn ni a pè ní ‘ọgbọ́n ìṣẹ̀dá’, àwọn àbùdá tí ó sì jẹ́ àwòmọ́ ìdájọ́ ni a tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí ‘àwòmọ́ afọ̀’. Àwọn kókó-èrò méjì yìí ni ó dàbí òpó tí ó di lítíréṣọ̀ Yorùbá mú. Lámèétọ́ sì lè ṣe àmúlò wọn gẹ́gẹ́ bí tíọ́rì tàbí ìlànà tí yóó le ṣe àyẹ̀wò aáyan apohùn àti ìmúradè àwọn òǹwòran tàbí òǹgbọ́. A ṣe àmúlò ọ̀kan-ò-jọ̀kan àwọn ìpohùn Yorùbá bí oríkì, àlọ́, òwe, ewì àwíṣẹ, ewì ajẹmọ́fá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, fún ìtúpalẹ̀ àti àlàyé nínú iṣẹ́ yìí. A sì lo ìlànà fọ́múlà ìpohùn (oral formulaic approach) gẹ́gẹ́ bí ojúpọ̀nnà ìtúpalẹ̀. Iṣẹ́ yìí jẹ́ kí ó hàn pé ṣíṣe àwọ̀pọ̀ ọgbọ́n ìṣẹ̀dá àti àwòmọ́ afọ̀ fún ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ alohùn yóó ṣe ìhújáde àwọn àwòmọ́ ajẹmẹ́wà ìpohùn Yorùbá àti ti Áfíríkà lápapọ̀.

**ORO KOKO**
Litireso, Oriki, Ogbon Agbekale, Ibile Enu

**RESUMO**
A criação de qualquer gênero literário começa com uma intenção criativa, que requer a imaginação e a criatividade do artista literário. Quando uma criação literária está completa, ela possui certas características e critérios que o artista literário deve seguir na produção de seu discurso ou performance. Isso ocorre porque esses critérios são os critérios de julgamento, que os espectadores ou ouvintes usam como padrão ou critério para julgar um tipo específico de discurso ou performance. Os vários propósitos que os poetas usam para criar poesia são chamados de "sabedoria criativa", e as qualidades que são a base do julgamento são chamadas de "critérios". Esses dois conceitos são como pilares que sustentam a literatura iorubá. Lamèèto pode usá-los como uma teoria ou princípio que pode analisar a escolha da poesia e a preparação dos espectadores ou ouvintes. Uma variedade de poesia iorubá, como poesia, enigmas, provérbios, poemas poéticos, epigramas e assim por diante, são usados para análise e explicação neste trabalho. A abordagem oral formulaica foi usada como estrutura analítica. Este trabalho demonstra que a combinação das abordagens naturalista e teórica para a análise da literatura oral produzirá um conjunto abrangente de tradições orais iorubás e africanas.

* Department of Linguistics and Nigerian Languages,Ladoke Akintola University of Technology, Ogbomoso, E-mail: alademuyiwa@lautech.edu.ng; adewaleademuyiwa5@gmail.com

**PALAVRAS-CHAVE**
Literatura, Poesia, Sabedoria cirativa, Tradição oral

**Ìfáárà**

Ìgbéjáde afọ̀ ajẹmọ́ lítíréṣọ̀ kì í ṣe ohun àkùùgbù tàbí àkánjú ṣe. Ó ní àwọn ìgbésẹ̀ tí ó máa ń wáyé ṣáájú ìgbé jáde afọ̀ ajẹmọ́ lítíréṣọ̀. Àwọn ìgbésẹ̀ yìí sì ṣe pàtàkì nínú ìwáyé lítíréṣọ̀. Ìlànà tí afọ̀ lítíréṣọ̀ ń gbà wáyé ni a lè tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí ìgbésẹ̀ ìṣẹ̀dá iṣẹ́-ọnà ajẹmọ́ lítíréṣọ̀, èyí tí o jẹ mọ́ akitiyan èrò-ọkàn, ọpọlọ àti ìfaraṣe apohùn, láti ibi àrògún títí de orí ìgbéjáde afọ̀. Ó hàn pé láti ibi ìṣẹ̀dá afọ̀ yìí ni gbogbo afọ̀ tí máa ń wáyé. Irúfẹ́ àwọn àbùdá yìí ni a sì lè pè ní àbùdá ìṣẹ̀dá lítíréṣọ̀ alohùn (oral formulaic). Nígbà tí afọ̀ bá kẹ́sẹ járí nínú ìṣẹ̀dá, ó ní àwọn àwòmọ́ tí apohùn gbọdọ̀ palẹ̀mọ́ fún, nítorí àwòpọ́ ni wọn yóó jẹ́ odìwọn ìgbéléwọ̀n pẹ̀lú ìpohùn rẹ̀. Àwọn ohun tí ó mu nǹkan wọ̀nyí jẹ́ ẹ̀ka ìmọ̀ ìṣọwọ́lò-èdè tí lámèétọ́ gbọdọ̀ fi ọkàn sí nínú àgbéyẹ̀wò ìwáyé lítíréṣọ̀ alohùn.

Iṣẹ́-ọnà ni gbogbo ohun tí ó bá ti jẹ mọ́ ọgbọ́n àtinúdá, tí ó sì ni ète ìṣẹ̀dá. Èyí lè jẹ́ ọnà igi gbígbẹ́, amọ̀ mímọ, irin rírọ, ilé kíkọ́, àwòrán yíyà, ohun pípè àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. ní àwùjọ Yorùbá, oníruurú iṣẹ́ ọnà ni ó wà, gbogbo àwọn ẹ̀ka-iṣẹ́ ọnà yìí ni ó sì máa ń fi àwọn ẹ̀yà Yorùbá hàn gẹ́gẹ́ bí alátinúdá àti aṣẹ̀dá. Ọ̀rọ̀ nípa pé àwọn ẹ̀yà Yorùbá mú ọ̀rọ̀ ìṣẹ̀dá iṣẹ́-ọnà ní ọ̀kúnkúndùn hàn nínú àlàyé Ademuyiwa (2022: 1) gẹ́gẹ́ bí ó ṣe fi èrò Akìwọwọ hàn pé:

> Ọ̀rọ̀ nípa pé àwọn Yorùbá ní agbára ìṣẹ̀dá nǹkan hàn nínú àlàyé Akìwọwọ (1986). O tọ́ka pé aṣẹ̀dá ni àwọn Yorùbá. Wọ́n ń ṣẹ̀dá ijó, wọ́n ń ṣẹ̀dá ìlú, wọ́n ń ṣẹ̀dá orin, wọ́n ń ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀.

Àlàyé òkè yìí fi hàn pé ojúkan kò ṣeé wo agbára ìṣẹ̀dá àti iṣẹ́-ọnà ní àwùjọ Yorùbá, àti pé ṣíṣẹ̀dá nǹkan ti di bárakú fún wọn. Gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú àlàyé náà, orígun kan pàtàkì ni ìṣẹ̀dá ohùn tàbí ọ̀rọ̀-ẹnu jẹ́ nínú iṣẹ́-ọnà ní àwùjọ àwọn Yorùbá. Ademuyiwa (2022: 1) ṣe àlàyé nípa ìpìlẹ̀ fún afọ̀ alohùn tí à mọ̀ sí ìpohùn Yorùbá nígbà tí ó sọ pé:

> Ọ̀rọ̀ nípa ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ yìí ló jẹ́ ìpìlẹ̀ fún gbogbo afọ̀ alohùn Yorùbá pátá. Ọ̀rọ̀ sísọ ní wọ́n gbára lé, ohùn-ẹnu ni wọ́n sì fi ń gbé wọn jáde. Wọ́n tilẹ̀ máa ń pe àwọn apohùn Yorùbá ní sọ̀rọ̀sọ̀rọ̀. Èyí fi hàn pé alátinúdá, aṣẹ̀dá àti alágbẹ̀dẹ-ọ̀rọ̀ ni àwọn ẹ̀yà Yorùbá jẹ́. Àwọn ohun tí wọ́n sì ń lò gẹ́gẹ́ bí èròjà fún ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ yìí ni ẹ̀bùn èdè, ìrírí, ọgbọ́n àtinúdá, èrò, ìsípayá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Àlàyé òkè yìí fi hàn pé ó ni àwọn èròjà kan tí ó máa ń ṣe atọ́nà fún ìgbéjáde iṣẹ́-ọnà ajẹmọ́-ohùn. Lára àwọn èròjà náà sì ni ẹ̀bùn èdè, ìrírí, ọgbọ́n àtinúdá, èrò, ìsípayá. Èyí ni pé apohùn tí yóó pe ohùn ní àwùjọ Yorùbá gbọdọ̀ ní ẹbùn èdè nítorí pé èdè yìí ni yóó fi ṣe àgbékalẹ̀ ìpohùn rẹ̀. Bí kò bá sì gbọ́ èdè ní àgbọ́dájú, àgbékalẹ̀ rẹ̀ lè mẹ́hẹ. Ìrírí ni ó máa ń jẹ́ kí apohùn ní ìmọ̀ nípa ohun tí yóó jẹ́ àkóónú ewì rẹ̀ gan-an, ìdí sì nìyí tí ó fi máa ń jẹ́ ìṣòro fún ẹnìkan láti sọ̀rọ̀ lórí ohun tí kò bá ní ìrírí nípa rẹ̀. Ọgbọ́n àtinúdá ni apohùn máa ń lò láti ṣe àtúndá àti àtúnrọ ìrírí tí ó ń fi èdè gbé jádé, èrò sí ni yóó fi lè ronú jinlẹ̀ nípa àwọn ohun tí ó bá fi ìrírí ara rẹ̀ kó jọ. Iṣípayá ni ìmísí tí ó máa ń jẹ́ kí àtòpọ̀ àti àlòpọ̀ àwọn nǹkan wọ̀nyí rọrùn fún apohùn.

**Àṣà Ìpohùn ní àwùjọ Yorùbá**

Àṣẹ̀ṣẹ́dáyé àwọn ẹ̀yà Yorùbá ni gbogbo tí ó jẹ mọ́ ọ̀rọ̀ alohùn ti wà pẹ̀lú wọn. Èyí ni pé gbogbo ètò ìgbè-ayé wọn tí ó jẹ mọ́ ìtàn, ọnà, ewì, ẹ̀sìn, ẹ̀kọ́ ìhùwàsí, fókìlọ̀ọ̀, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, gbára lé ohùn-ẹnu, èyí tí a mọ̀ sí oral tradition. Èyí túmọ̀ sí pé inú akoto afọ̀ olohùn ni gbogbo ètò ìgbè-ayé wọn wà. Èrò nípa èyí hàn nínú àlàyé tí Táíwò nínú Ademuyiwa (2017: 5) ṣe pé:

> Oral traditions form an integral part of the culture of any group of people. Before printing was invented communities sought to preserve their identity as groups by handing down orally from one generation to another the most important elements of their culture.
> (Àṣà ìpohùn jẹ́ ọ̀kan nínú àṣà tí ó pa àwọn ẹ̀dá ènìyàn àwùjọ kan pọ̀. Kí ó tó di pé àṣà àkọsílẹ̀ dé ọ̀nà tí àwọn àwùjọ ń gbà ṣe àwọn ohun ìdámọ̀ wọn lọ́jọ̀ ni jíjẹ́ kí àwọn ohun tí ó ṣe pàtàkì nínú àṣà wọn wà ní alohùn láti ìran kan sí ìran mìíràn.)

Àlàyé Táíwò nínú Ademuyiwa (2017) òkè yìí fi hàn pé ìpohùn ko ipa púpọ̀ nínú ìgbáyégbádùn àti ìtẹ̀síwájú àwùjọ Yorùbá. Èyí jẹ́ kí ó hàn pé gbogbo ìlànà ìgbé-ayé yóòwú ó jẹ́ bí ìmọ̀ mọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà, ìmọ̀ ẹ̀rọ̀, ìwé kíkọ, títẹ̀ àti kíkà, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, ti a lè bá pàdé ní àwu`jọ Yorùbá lóde-òní bá àṣà ìpohùn ní àwùjọ Yorùbá. O tún nínú àlàyé Táíwò nínú Ademuyiwa (2017: 5) pé àwọn àṣà ìgbàlódé gan-an kò gba àṣà ìpohùn kúrò ní àwùjọ àwọn Yorùbá. Èyí hàn nígbà tí ó sọ pé:

> Even since the invention of printing, oral literature in Africa has not died out. In the first place, much of the material could not be printed. Secondly, even if some of the material was printed, there was still widespread illiteracy and poverty. It was only orally that the elders in the community could continue to transmit to the young ones the customs, beliefs and expectation of the race.
>
> (Kódà láti ìgba tí àṣà àkọsílẹ̀ ti dé, lítíréṣọ̀ alohùn ní ilẹ̀ Adúláwọ̀ kò kú. Lọ́nà kìn-ín-ní, púpọ̀ ohun tí ó wà nínù rẹ̀ kò ṣe é kọ sílẹ̀. Lọ́nà kejì, bí wọ́n bá tilẹ̀ kọ wọ́n sílẹ̀, àìní ìmọ̀ ẹ̀kọ́-ìwé àti àìrówó sì wọ́pọ̀ láàárín àwùjọ. Ọ̀nà alohùn nìkan ni àwùjọ ń ṣàmúlò fún ìtànkálẹ̀ àṣà ìgbàgbọ́ àti èròǹgbà wọn fún awọn èwé ìran ọ̀hún).

Lódè òní, à kò gbà pé àìní ìmọ̀ ẹ̀kọ́-ìwé àti àìrówó ni kò jẹ́ kí àwọn Yorùbá fi àṣà ìpohùn sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àlàyé Táíwò. Bí èyí bá rí bẹ́ẹ̀ ní nǹkan bí ọdún 1967 tí Táíwò gbé iṣẹ́ rẹ̀ jáde, ó hàn gbangba pé kò sí ohun tí ó jọ àìnì ìmọ̀ ẹ̀kọ́-ìwé àti àìrówó ní òde-òní. Ohun kan gbóògì tí a sì lè sọ pé ó fa èyí pé àṣà ìpohùn ti di bárakú fún àwọn ẹ̀yà Yorùbá. Lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ kò sì le è fẹsẹ̀ múlẹ̀ dáadáa, láìṣàmúlò ìlànà alohùn fun ìdí pàtàkì yìí. Ademuyiwa (2017: 4) sọ nípa èyí pé:

> Ewì alohùn ni ìbẹ̀rẹ̀ ewì àwọn Yorùbá, nígbà tí ọ̀làjú sì dé ni wọ́n káṣà kíkọ ewì àpìlẹ̀kọ́. Nínú àṣà Yorùbá, akéwì máa ń ke ewì rẹ̀ faráyé gbọ́ ni. Ìlànà yìí sì ni gbogbo akéwì alohùn pátá láwùjọ Yorùbá ń ṣàmúlò nínú ìgbéjáde ewì wọn. Sùgbọ́n nínú àṣà

> Òyìnbo, àkọjùsílẹ̀ ni wọ́n máa ń kọ ewì wọn, ẹni tí ó bá sì wù ni yóò lọ mú irúfẹ́ ewì bẹ́ẹ̀ tí yóò sì kà á. Nígbà ti àṣà ewì àpilẹ̀kọ dé àwùjọ Yorùbá, àkọjùsílẹ̀ ni àwọn náà ń kọ ọ́, ẹni tó bá rí kó kà á náà ni àwọn akéwì ti ó kọ́kọ́ gùnlé ìlànà yìí fi ṣe, ṣùgbọ́n nígbà tí ó yá, tí ìlànà yìí kò rọrùn fún àwọn Yorùbá tó, àwọn akéwì bẹ̀rẹ̀ sí í gbé ewì tí wọ́n bá ko lọ sí orí rẹ́díò àti tẹlifísàn láti ka àwọn ewì tí wọ́n bá kọ sétí aráyé. Bí wọ́n bá ń ka àwọn ewì yìí, wọ́n máa ń ṣàmúlò ohùn dídùn tí wọ́n ni, èyí ló sì pìlẹ̀ kíké ewì alohùn ìgbàlódé láwùjọ àwọn Yorùbá.

Ó tún hàn pé lẹ́yìn tí ìmọ̀ ẹ̀kọ́-ìwé wọ àwùjọ Yorùbá, tí wọ́n sì bẹ̀rẹ̀ àṣà mọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà, èyí tí ó bí lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ, lórí bátánì ìmọ̀ àti lítíréṣọ̀ alohùn wọn náà ìṣẹ̀dá àwọn afọ̀ àpilẹ̀kọ yìí gbára lé. Èyí ȟàn nínú erò Ìṣọ̀lá (1978: 1) pé:

> Òkẹ́rẹ́ jọkún
> Ológinní jògbo
> Àdan ò yàtọ̀ sóòbẹ̀ láàjìn
> Ọmọ tá a bá bi tó jẹ́ tẹni
> Gbogbo ara ní í fí í jọ'ni
> Ẹ ó ti ṣàròfọ̀ kó má fara jewì?
> Bátànì tó wà ni tàdáyébá
> Nì ò farahàn mọ́ l'óde òní.

Èrò òkè yìí fi hàn pé aṣọ ewì alohùn ni bùbá àti sòkòtò tí ewì ìgbàlódé ń wọ̀. Èyí fi hàn pé ọmọ tí ewì alohùn bí ni ewì àpìlẹ̀kọ jẹ́. Àrífàyọ inú èyí ni pé àṣà ìpohùn ni olúborí ìlànà ìmọ̀ yòówù kí ó jẹ́ ní àwùjọ àwọn Yorùbá. Fún ìdí èyí, ọmọ tí ewì alohùn bí ni ewì àpilẹ̀kọ ní àwùjọ Yorùbá.

Ohun mìíràn ni ó tún fi ìdí èyí múlẹ̀ ni ọ̀rọ̀ ni ewì alohùn ìgbàlódé, èyí tí ó ní í ṣe pẹ̀lú fífe ohùn gbé ewì ìgbàlódé jáde. Ìdàgbàsókè mìíràn tí ó dé bá ewì alohùn ní àwùjọ Yorùbá ni ewì alohùn ìgbàlódé yìí, ó sì ṣe àfihàn ipò tì àṣà ìpohùn wa` ní àwùjọ Yorùbá. Nígbà tí àṣà ìmọ̀ ẹ̀kọ́-ìwé wọ ilẹ̀ Yorùbá, tí kíkọ ewì sí inú ìwé sì bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹu, ni àwọn akéwì àpilẹ̀kọ kan bí Adébáyọ̀ Fálétí, Ọláńrewájú Adépọ̀jù, Ọlátúbọ̀sún Ọládàpọ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, bẹ̀rẹ̀ sí ní gbé ewì tí wọ́n kọ sílẹ̀ lọ sí orí rédíò àti tẹlifísàn, tí wọ́n sì bẹ̀rẹ̀ sí í fi ohùn-ẹnu kà á jáde (Ọlátúnjí 1982, Ajíbádé àti Rájí 2011, Adémúyìwá 2017, abbl.).

Èyí ni pé ìrìn-àjò ewì ní àwùjọ Yorùbá bẹ̀rẹ̀ láti orí ẹnu, ó dé inú ìwé, ó sì tún padà sí orí ẹnu nípasẹ̀ rédíò àti tẹlifísàn. Kò dúró síbẹ̀, ó tún tẹ̀síwájú dé ibi kíká sí orí fọ́nrán ọ̀dìò. Lẹ́yìn èyí ni ó tún dé orí fọ́nrán fídíò, kí ó tó tún wá dé orí ìkànní ìgbáfẹ́ (social media) lóde-òní. Gbogbo èyí fi pàtàkì àṣà ìpohùn hàn nínú ìgbéjáde àwọn iṣẹ́-ọnà ajẹmóhùn ní àwùjọ Yorùbá, ó sì jẹ́ kí ó hàn pé bí ìgbà ṣe ń yí ni ewì alohùn Yorùbá ń bá ìgbà yí gẹ́gẹ́ bí ohun tí ó ti di bárakú fún àwọn Yorùbá.

Fún ìdí èyí, ó hàn gbangba pé ọ̀rọ̀ afọ̀ alohùn ní àwùjọ Yorùbá ju ọ̀rọ̀ àwọn ewì ìbílẹ̀ nìkan lọ, gbogbo àwọn ẹ̀yà lítíréṣọ̀ tí ó bá ti ṣeé gbọ́ sétí ni a lè tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí lítíréṣọ̀ Yorùbá. Àwọ̀pọ̀ gbogbo irúfẹ́ àwọn ẹ̀yà lítíréṣọ̀ wọ̀nyí ni ó sì jẹ́ iṣẹ́ ìwádìí yìí lógún.

**Tíọ́rì Àmúlò - Ìlànà Fọ́múlà Ìpohùn (Oral Formulaic Approach)**

Tíọ́rì tí a ṣe àmúlò fún àgbéyẹ̀wò iṣẹ́ yìí ni tíọ́rì Fọ́múlà Ìpohùn, èyí tí a mọ̀ sí oral Formulaic Theory. Tíọ́rì yìí jẹ́ tíọ́rì tí ó ń ṣe ìwádìí nípa àwọn àbùdá ìdámọ̀ àti ìlànà ìṣẹ̀dá àwọn ẹ̀yà afọ̀ alohùn kọ̀ọ̀kan. Ẹni tí ó dá tíọ́rì yìí sílẹ̀ ni Parry Milman Èrò nípa àgbéyẹ̀wò àbùdá ẹ̀yà ìpohùn Homer ni ó sì ṣe atọ́kùn ìdásílẹ̀ rẹ̀. Àwọn onímọ̀ tí wọ́n tún jẹ́ agbátẹ̀rù tíọ́rì yìí ni Lord Albert ati Foley John Miles. Ohun tí ó jẹ́ ìlépa tíọ́rì Fọ́múlà Ìpohùn nínú ìtúpalẹ̀ iṣẹ́-ọnà ajẹmọ́-lítíréṣọ̀ ni aáyan láti ṣe àgbéyẹ̀wò àti ìtúpalẹ̀ sítáì afọ̀ kọ̀ọ̀kan. Èyí

hàn pé àwọn ohun tí ó jẹ mọ́ sítàì afọ̀ náà ni abùdá afọ̀ tí a lè pè ní fọ́múlà rẹ̀. Àbúdà afọ̀ wọ̀nyí náà si ni a lè ní Fọ́múlà Ìpohùn.

**Ọgbọ́n ìṣẹ̀dá**

Ninú ètò ìṣẹ̀dá afọ, ọgbọ́n ìṣẹ̀dá jẹ́ ète tí àwọn àpohùn máa ń lò láti gbé afọ̀ ohun rẹ̀ jáde. Irufẹ́ ọgbọ́n ìṣẹ̀dá gbára lè ohun tí wọn ń pè ní literary canon, èyí tí a lè túmọ̀ sí òtè tàbí ète ìpohùn. Òté tàbí ọ̀te ìpóhùn yìí tí ìwàyé afọ̀ alohùn ń tọ̀, kí ìgbéjáde rẹ̀ tó ojú-òpó lè wáyé. Burke (2014 :21) ṣe àlàyé pé ìgbesẹ̀ márùn-ún ni òte ìpohùn tí ó pè ní canon yìí jé. Àwọn òté máràárún náà ni :

1. Discovery or invention stage (ìpele ìwárí tàbí ìṣẹ̀dá)
2. Arrangement stage (ìpele àtúntò)
3. Stylisation stage (ìpele ìṣọ́wọ́lò/ìdáràsí)
4. Memorisation stage (ìpele ìhásórì)
5. Delivery stage (ìpele ìgbéjáde)

Ní ìbámu pẹ̀lú lítíréṣọ̀ alóhùn Yorùbá, gbogbo àwọn kókó-èrò yìí ni a ó gbé yẹ wò gẹ́gẹ́ bí wọn ṣe jẹ mọ ìṣẹ̀dá afọ̀ alohùn Yorùbá

**Ìpele Ìwárí tàbí Àrògún - Ìhunpọ̀-Èrò**

Èyí jẹ mọ́ àrògún apohùn láti ṣe àwàrí nǹkan ọ̀tun tí yóó gbé yọ gẹ́gẹ́ bí ọ̀tun afọ̀. Èyí ni pé apohùn yóó ṣe àwàrí ìṣẹ̀dá nǹkan tuntun. Iṣẹ́ apohùn ni láti ṣe àwárí ohun tí ẹnìkan kàn kò tíì ṣe rí tàbí láti wá ọ̀nà àrà mìíràn láti gbé ohun tí ẹnìkan ti ṣe rí yọ, ó ni àwọn nǹkan pàtàkì tí wón máa ń ṣe ìrànwọ́ fún apohùn fún àwárí àti ìṣẹ̀dá ohun ọ̀tun. Lára àwọn nǹkan bẹ́ẹ̀ ni èrò, ìrírí àti ìṣẹ̀lẹ̀ àti ìsípayá.

**Èrò**

Àyọrísí iṣẹ́ ọpọlọ láti àròkàn dé àrògún ni à ń pè ní ewì (Ọ̀pẹ́fèyítìmí nínú Ológundúdún 2009: V). Ohun tí èyí ń sọ ni pé kí iṣu tó diyán, a gún iṣu lódó, kí ègbodò tó di èlùbọ́, ó ṣe ṣáà lóóòrùn, kí a to le pe ewì ni ewì, ọpọlọ yóò ti ṣiṣẹ́ èrò ènìyàn yóó sì ti ròkun rọ̀sà, ọpọlọ wá ṣíṣẹ́, ó ṣìsẹ́ tán, èrò ènìyàn si ròkun rọ̀ṣà, o bọ, àbájáde rẹ̀, ewì ni. Èrò ni ó máa ń ṣáájú ìṣẹ̀dá afọ̀ alohùn yòówù kí ó jẹ́. Èyí sì máa ń jẹ́ ìrònùjìnlẹ̀ apohùn láti gbẹ́ iṣẹ́-ọnà jáde. Ọ̀nàkọnà ni èrò lè gbà dé inú apohùn, èyí ni pé kí apohùn kan ronú lọ lórí nǹkan kan pàtó. Ìrírí apohùn àti ohun tí ó ṣẹlẹ̀ náà lè bí èrò fún apohùn. Èyí ni Adépọ̀jù (1972) pè ní ìdúrówòye pẹ̀lú àlàyé pé òun ni ó máa ń ṣíde ìgbésẹ̀ èrò nínú ìṣẹ̀dá afọ̀.

**Ìrírí**

Ìrírí apohùn`ti àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ń ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́ láàrìn àwùjọ àti tí ó ti sẹlẹ̀ sẹ́yìn, máa ń wà nínú ohun tí ó máa ń jẹ́ àhunpọ̀-èrò fún apohùn. Apohùn sì tún lè ronú nípa fífí ojú-inú wo ohun tí ó ṣeé ṣe kí ó ṣẹlẹ̀ lọ́jọ́ iwájú. Ìdí nìyí tí ó fi ṣe pàtàkì fún apohùn tàbí aṣẹ̀dá afọ̀ ajẹmọ́-ohùn láti kọbi ara sí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú àwùjọ nítorí pé àwọn ni wọn yóò jẹ́ èròjà fún ìhunpọ̀ èrò rẹ̀. Ó hàn pé kì í ṣe gbogbo ìrírí tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ni apohùn lè múlò nínú ìṣẹ̀dá ìpohùn rẹ̀. Èrò yìí hàn nínú àlàyé Fálétí nínú Ọlátúnjí (1982: 1) pé:

> Omi tí kò jàgbẹ̀ lójú
> Ó le dẹ́nu akéwì kó dòkun
> Ó le dẹ́nu akéwì kó dọ̀sà
> Ẹ̀fúùfù tó sì ń mòkun mọ̀sà
> Ó le dénú akéwì
> Kó má joru ẹnu lọ
> Inú akéwì gbọ̀sẹ̀
> Inú akéwì gbèéwú
> Inú akéwì sì gbomi tó mọ́ taara

Èrò Fálétí òkè yìí fi hàn pé gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀ kọ́ ni ó lè fún aṣẹ̀dá afọ̀ ní ìṣípayà láti ṣẹ̀dá afọ̀. Ohun tí àwùjọ kà kún nǹkan bàbàrà lè má ju bínńtín lójú apohùn, ohun tí àwùjọ sì ń fi ojú kékeré wò lè jẹ́ ohun tí ó tóbi ràbàtà lójú apohùn. Ohun tí èyí túmọ̀ si ni pé kì í ṣe gbogbo ìrírí ni akéwì lè lò láti ṣẹ̀dá afọ̀.

**Ìsípayá**

Ìsípayá ni a lè pè ní ẹ̀gùn afọ̀. Ó jẹ́ ìmísí tí ó máa ń dé ara àpohùn tí àlopò gbogbo àwọn èròjà ìṣẹ̀dá fi máa ń rọ apohùn rọ́rùn. Èyí ni pé ìsípayá ni ó dàbí ẹ̀gùn tí apohùn ń gùn tí apohùn fi máa ń ṣẹ̀dá afọ̀ ipohùn ní ọ̀nà-àrà. Èyí ni Ìṣọ̀lá (1984) tọ́ka sí nígbà tí ó sọ pé "òrìṣà wo ló ń gun àwọn òǹkọ̀wé Yorùbá". Àlàyé tí a ni láti ṣe sí èrò Ìṣọ̀lá (1984) ni pé kì í ṣe àwọn òǹkọ̀wé Yorùbá nìkan ní ó máa ń rí ìṣípayá, àwọn aṣẹ̀dá afọ̀ alohùn náà máa nílò ìṣípayá látí lè pe ohùn, ṣùgbọ́n ohun tí ó jẹ́ kí ó sọ bẹ́ẹ̀ ni pé lórí lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ ni ó ni ó gbé iṣẹ́ rẹ̀ lé. Ọ̀pádọ̀tun (2003: 51), sọ pé:

> Ohun tí a lè pè ní ìsípayá akéwì gẹ́gẹ́ bí àlàyé tí a ti ṣe sẹ́yìn ni ìwárapàpà ti akéwì máa ń ní tí ó fi máa ń ké tàbí kọ́ ewì rẹ̀.
>
> ...
>
> Ní àsìkò yìí àwọn kọ́ ni wọ́n ni ara wọn, nǹkan tí a kò mọ̀ lo máa ń yá wọn lò. Nǹkan yìí ni àwọn mìíràn pè ní òrìṣà, àwọn kan ní ẹ̀mí ni.
>
> ...
>
> Ohun tí ó sáà dájú ni pé ìṣesí akéwì lásìkò tí ó bá wà lórí ẹ̀gùn jọ ti olórìṣà tí òrìṣà ń gùn tàbí, tí ẹlẹ́sìn tí ẹ̀mí mímọ́ ń lò.

]Àlàyé Ọ̀pádọ̀tun (2003) òkè yìí fi hàn pé ìṣípayá jẹ́ ẹ̀mí tí ó máa ń bà lé apohùn tí apohùn fi máa ń pe ohùn ní ọ̀nà tí ó jọ arayé lójú. Èyí jẹ́ kó hàn pé ìṣípayá ni yóó darí apohùn tí yóó fi ṣe àmúlò gbogbo àbùdá ìṣẹ̀dá ìpohùn rẹ̀ tí wọn kò sì ní tako ara wọn.

Ó hàn nínú àlàyé yìí pé ìwàrí ohun tí apohùn fẹ́ ṣẹ̀dá àti ìlànà tí yóó gbà ṣẹ̀dá rẹ̀ ni ó máa ń jẹ́ ìgbésẹ̀ kìn-ín-ní nínú ìgbéjade lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá. Lára ohun tí ó sì máa ń ṣe iṣẹ́ ni ọgangan-ipò yìí ìrònú, ìrírí, ìṣẹ̀lẹ̀ àti ìsípayá. Gbogbo àwọn nǹkan wọ̀nyí ni a sì tọ́ka sí gẹgẹ́ bí ìhunpọ̀-èrò nínú ìwàrí àti ìṣẹ̀dá lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá.

**Àtúntò Afọ̀**

Lábala-lábala ni ìṣẹ̀dá afọ̀ máa ń wá erò apohùn. Èyí ni pé kì í ṣe odidi lẹ́ẹ̀kan ṣoṣo ni odidi afọ̀ máa ń sọ̀ kalẹ̀ sí ọpọlọ aṣẹ̀dá-afọ̀. Nígbà tí aṣẹ̀dá afọ̀ bá ti ṣe àwárí afọ̀ ìpohùn tí ó fẹ́ gbé jáde, tí ó sì ti ṣẹ̀dá rẹ̀, ohun tí ó máa ń kàn ni kí ó ṣe àtúntò àwọn èròjà àròfọ̀ tí ó kó jọ. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí ìwáléra afọ̀ nígbà tí aṣẹ̀dá-afọ̀ bá ń ṣẹ̀dá afọ̀ lè má tẹ́ẹ́ aṣẹ̀dá-afọ̀ lọ́rùn tàbí kí afọ̀ nílò àwọn àtúnṣe pẹ́ẹ́ pẹ̀ẹ̀ pẹ́ẹ́ kan. Bí èyí bá wáyé, ní ìpele àtúntò-afọ̀ ni aṣẹ̀dá-afọ̀ yóó ti tún afọ̀ rẹ̀ tó sí bí ó ṣe fẹ́ kí wọ́n wáyé tẹ̀lé ara wọn.

**Ìṣọ́wọ́lò Afọ̀**

Afọ̀ lítíréṣọ̀ kì í ṣe afọ̀ tí ó ma ń dúró lọ́bọrọgidi, ónírúuru sítáì àti àrà ni ó máa ń wọnu. Èyí sì máa ń fi aṣẹ̀dá-afọ̀ hàn gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó ní ẹ̀bùn ìṣẹ̀dá. Lára àwọn nǹkan tí apohùn máa ń ṣe lọ́jọ̀ nínú ìṣọwọ́lò afọ̀ ni àbùdá àdámọ́ afọ̀, bátánì afọ̀, ìhun afọ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nínú ìṣẹ̀dá afọ̀ alohùn Yorùbá, ẹ̀yá afọ̀ kọ̀ọ̀kan wà tí ó jẹ́ pé apohùn tí ó bá ń ṣẹ̀dá

irúfẹ́ afọ̀ bẹ́ẹ̀ kò ni omínìrà láti fi àtinuda ara rẹ̀gbé ìhun afọ̀ kalẹ̀. Irúfẹ́ àwọn afọ̀ báyìí ni a lè pé ni afọ̀ ajẹmọ-ìhun-àìgbẹ̀fẹ̀. Lára irúfẹ́ ìpohùn tí ó wà ní ìpín yìí ni àló, ẹsẹ̀-ifá, òwe, oríkì àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Irúfẹ́ àwọn afọ̀ wọ̀nyí ní àwọn àbùdá tí a fi lè dá wọn mọ́ èyí tí a lè pè ní fọ́múlà ìṣẹ̀dá wọn. Ìdí nìyí tí Ọlátúnji (1984) fi pé àwọn afò báyìí ni features types, èyí tí a lè pè ní afọ̀ ajẹmọ́-àbùdá. Àwọn àbùdá wọ́n máa ń jẹ́ àbùdá tí ó dá wọn yàtọ̀ gedengbe sí ẹ̀yà ìpohùn mìíràn. Ibi àwọn àbùdá yìí sì ni fọ́múlà ìpohùn wọn ti máa ń jẹ yọ. Bí àpẹẹrẹ, àwọn àbùdá díẹ̀ nínú àwọn fọ́múlà ìṣẹ̀dá àwọn ẹ̀yà lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá kan ni ó wà ní àtẹ 1 yìí:

| Nánbà | Afọ̀ alohùn | Akópa | Fọ́múlà Ìṣẹ̀dá (Máyẹ̀) | Fọ́múlà Ìṣẹ̀dá mìíràn |
|---|---|---|---|---|
| 1 | Àlọ́ onítàn | Apàlọ́<br>Agbálọ̀ọ́ | Ààlọ́ ooo<br>Ààlọ̀ọ̀ | Burè méta – ìṣíde, àgbékalẹ̀ ìtàn, ìgúnlẹ̀. |
| 2 | Àlọ́ àpagbè | Apàlọ́<br>Agbálọ̀ọ́ | Ààlọ́ ooo<br>Ààlọ̀ọ̀<br>…kín ni oo? | Àdìtú ìbéèrè<br>Àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ |
| 3 | Ẹsẹ̀-ifá | Babaláwo<br>Oníbèéèrè | A díá fún/A dífá fún | Burẹ̀ méjọ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú Abimbọla (1967) tàbí burẹ̀ mẹ́fà gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú Ọlátúnjí (1984) |
| 4 | Òwe | Àgbàlagbà | Àwọn Yorùbá/àgbà máa ń pa òwe pe…<br>Òwe Yorùbá sọ pé…<br>…tótó ṣe bí òwe oo…<br>abbl... | Òwe lè jẹ́ gbólóhùn kan, gbólóhùn méjì, òwe alakanpọ abbl (Bamgbose, 1968), Olatunji, 1984), Olasebikan, 2025)) |
| 5 | Oríkì | Àwọn apohùn | Ìpèdè ajẹmébí – ọmọ, baba, ìyekan, ọlọ̀tan, abbl.<br>Ìsọdorúkọ | Iṣẹ́ ìran, èèwọ̀, ẹsin àwọn baba-ńlá, abbl<br>(Adémuyiwa, 2022) |
| 6 | Àrọ̀ | Ajárọ̀<br>Agbárọ̀ | Mo járọ́<br>Mo járọ̀ | Àdípèlé ìṣẹ̀lẹ̀ (episodic events)<br>Àdìtú ìtàn (Àjùwọ̀n, 2013). |

**Àtẹ 1**

Àtẹ òkè yìí ṣe àfihàn àwọn àṣàyàn lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá pẹ̀lú àwọn àbùdá ìmọ̀ ìṣọwọ́lọ̀-èdè tí ó jẹ́ fọ́múlà ìṣẹ̀dá wọn. Àtẹ náà tọ́ka sí àwọn tí ó jẹ́ akópa tàbí agbátẹ̀rù àwon ẹ̀yà ìpohùn Yorùbá wọ̀nyí. Àwọn fọ́múlà ìṣẹ̀dá tí wọ́n wà ní abẹ̀ fọ́múlà ìpohùn (máyẹ̀) ni wọ́n jẹ́ olúborí fọ́múlà ìṣẹ̀dá àwọn àṣàyàn lítíréṣọ̀ alohùn. Wọ́n jẹ́ fọ́múlà máyẹ̀ nítorí pé dandan ni kí wọ́n jẹ yọ nínú àwọn afọ̀ wọ́n jẹ mọ́. Àwọn fọ́múlà ìpohùn tí wọ́n wà ní abẹ́ fọ́múlà ìṣẹ̀dá mìíràn ni àwọn fọ́múlà ìṣẹ̀dá tí àwọn náà jẹ mọ́ àbùdà ìṣẹ̀dá afọ̀ tí wọ́n ti máa ń jẹ yọ, ṣùgbọ́n tí kò í òfin kan pàtó tí ó de ìrísí àti ìjẹyọ wọn nínú afọ̀.

Bákan náà, apohùn máa ná-án-ní èdè tí yóò fi ṣe afọ̀ rẹ̀ lóge. Èyí ni ó sì máa ń jẹ́ kí èdè lítíréṣọ̀ tàbí èdè ewì yàtọ̀ sí èdè ojoojúmọ́. Ìṣọ̀lá (1978:1) jẹ́ kó di mímọ̀ pé èdè akéwì, bí àwòrán àláràbarà ni, àtipé èdè tó wuyì ló máa n se atọ́kùn fún èrò. Adépọ̀jù (1972: 1) náà sọ pé: “akéwì ni ó máa ń fi ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ làákàyè ara rẹ̀ yí ọ̀rọ̀ ti o burẹ́wà padà sí èyí tí ó rẹwà lẹ́nu àti léti nípa ìdúrówòye àti àrògún”. Yíyí ọ̀rọ̀ tí o burẹ́wà padà sí arẹwà ọ̀rọ̀ tí Adépọ̀jù ń sọ ni Ìṣọ̀la pè ni àwòrán àràbanrà tí akéwì máa ń fi èdè yà. Èyí túmọ̀ sí pé àgbékalẹ̀ èdè làti ṣe ẹwà àti ọ̀ṣọ́ sí ọ̀rọ̀ lára ni a le pe ewi. Ìrú ìlànà àràbarabà àwòrán ti akéwì ń tẹ̀lé, tí wọn fi ń sọ àwọn èdè tó burẹ́wà di arẹwà èdè gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹ mọ́ ìlànà ìmọ̀ ìṣọwólò-èdè ní a fẹ́ ṣé àgbéyẹ̀wò àti ìtúpalẹ̀ rẹ̀ nínú iṣẹ́ yìí, gẹ́gẹ́ bí o ti jẹ́ mọ́ ewì

Ọláńrewàjú Adépọju; èyí sì ni èròǹgbà wa lóri iṣẹ ìwádìí yìí. Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2014: 85) ṣàlàyé pé:

> ....ẹnikẹ́ni tó bá ní àkíyèsí ni yóó le sọ pé a máa ń bá àwọn nǹkan kan nínú èdè ewì, tí yóò múni rò pé ó yàtọ̀ sí ti ojoojúmọ́, bí a kò tilẹ̀ tí ì le sọ ìyàtọ̀ yìí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́. Ohùn ewì ni àkíyèsí àkọ́kọ́ tó yẹ kó kọ́kọ́ hàn síni. Èyí ni ohùn orin, ti ìṣàré tàbí àwọn ọ̀rọ̀ abàmì tó n wọ́pọ̀ nínú ewì, èkejì ni ìlò àwọn wóróhùn lọ́nà tí yóó yàtọ̀ sí òfin èdè.


Àlàyé Ọ̀pẹ́fèyítìmí yìí ni pé ẹni bá dẹ ojú sílẹ̀ ni ó le rímú. Èyí túmọ̀ sí pé a ní láti ṣe àkíyèsí kí àwọn ìyàtọ̀ tí ó máa ń wà nínú èdè ewì àti èdè ojoojúmọ́ tó le fara hàn. Níbi ọ̀rọ̀ ìyapa yìí ni orígun tí ìmọ̀ ìṣọwọ́lò-èdè tí máa ń jẹ ìmọ ẹ̀dá-èdè lógún. Èyí sì jẹ ọ̀kan nínú àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tí a ó gbé yẹ̀wò nínú ìṣàtúpalẹ̀ wa.

Ohun mìíràn tí ó tún ṣe pàtàkì láti mẹ́nu bà nínú sítàì ìṣẹ̀dá lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ni ìwọ̀núbọ̀nú-afọ̀ (intertextuality), èyí tí ó jẹ mọ́ bí àwọn afọ̀ alohùn Yorùbá ṣe máa ń jẹ yọ nínú ara wọn. Jamil àti Yang (2012: 143) sọ nípa ìwọ̀núbọ̀nú-afọ̀:

> …through this we get the notion of intertextuality where a text is no longer independent but rather it is dependent upon other text whose author and origin are no more there.
> (…nípa èyí láti mọ̀ nípa iwọ̀núbọ̀nú-afọ̀ níbi tí afọ̀ kì í tì í ni òmìnira láti dádúró, ṣùgbọ́n tí yóò rọ̀gbọ̀kú lé afọ̀ mìíràn tí kì í ṣe orírun rẹ̀).

Àkíyèsí fi hàn pé ó fẹ́rẹ̀ má sí afọ̀ alohùn Yorùbá kan tí ó ní agbára láti dá dúró láìrọ̀gbọ̀kú lé afọ̀ mìíràn tàbí kí afọ̀ mìíràn rọ̀gbọ̀kú lé e. Ademuyiwa (2022: 226) ṣe àlàyé nípa èyí pé a lè pín afọ̀ kan sí ọ̀nà méjì. Ohun tí ó sọ ni pé:

> Ohun tí èyí fi hàn ni pé, a le pín odidi afọ̀ kan sí ọ̀nà méjì. Èyí ni afọ̀ ìpìlẹ̀/òpómúléró àti afọ̀ àfarahẹ. Afọ̀ ìpìlẹ̀ ni odo afọ̀ tí a gbá mú, tí à ń tú palẹ̀, èyí ni Adémúyìwà (2017) pè ní òpómúléró afọ̀, afọ̀ àfarahẹ ni àwọn afọ̀ tí ó rọ̀gbọ̀kú lé e, tí a le bá nínú rẹ̀, èyí ni Jamil àti Yang (2012) pè ni dependent text. Nípa lílo ìlànà ìwọ̀núbọ̀nú-afọ̀, a le lo àtẹ ìsàlẹ̀ yìí láti júwe oríṣìí àwọn àfọ tí a le bá nínú afọ̀ kan:




**Àtẹ 2**

Àlàyé òkè yìí fi hàn pé ẹ̀yà afọ̀ tí apohùn bá ń pè ohùn lé lórí gan-an ni afọ̀ ìpìlẹ̀, nígbà tí àwọn ẹ̀yà afọ̀ mìíràn tí ó bá jẹ yọ nínú rẹ̀ jẹ́ afọ̀ àfòmọ́. Ọlátúnjí (1982) ṣe àfihàn bí afọ̀ alohùn Yorùbá ṣe lè jẹ yọ nínú ara wọn gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú àtẹ 3 yìí:

| | Ọfọ̀ | Oríkì | Òwe | Ẹsẹ Ifá | Àlọ́ Àpamọ̀ |
|---|---|---|---|---|---|
| **Rárà** | + | + | + | - | - |
| **Ìjálá** | + | + | + | + | - |
| **Ẹ̀sà** | + | + | + | - | - |
| **Ẹkún Ìyàwó** | + | + | + | + | - |
| **Iyẹ̀rẹ̀ Ifá** | + | + | + | + | - |

**+ akàn (occurs)  - ẹja (doesn't occur)**

**Àtẹ 3**

Èrò Ọlátúnjí (1982) òkè yìí fi hàn pé kì í ṣe gbogbo àwọn ẹ̀yà lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ni wọ́n lè jẹ yọ nínú ara wọn. Àwọn ibi tí wọ́n ti lè jẹ yọ nínú ara wọn ni àmì ẹja (+) dúró fún, nígbà tí àmì akàn (-) dúró fún àwọn ibi tí wọn kò ti lè jẹ yọ. Àpẹẹrẹ ìwọ̀núbọ̀nú-afọ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe ń jẹ yọ nínú ìṣẹ̀dá lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ni ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí:

À ń kì í
À ń ṣà á
O níwọ ò mẹni tó kú
Wọ́n ni abiṣu gbọọrọ-gbọọrọ lóko
Abàgbàdo bọ̀kùà-bọ̀kùà láàlà
Ó tún ní ṣé ọdẹ ni àbí àgbẹ̀

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé òwe ni odidi afọ̀ òkè yìí, síbẹ̀, afọ̀ tí ó jẹ mọ́ oríkì jẹ yọ nínú rẹ̀. Bí ènìyàn bá pe afọ̀ náà láti òkè délẹ̀, ó hàn gbangba pé òwe ni a ó sọ pé onítọ̀hún pa, ṣùgbọ́n ìpèdè 'abiṣu gbọọrọ-gbọọrọ lóko' àti 'Abàgbàdo bọ̀ọ̀kùà-bọ̀ọ̀kùà láàlà' jẹ́ ẹ̀yà oríkì tí ó jẹ yọ nínú afọ̀ náà. Ohun tí ó sì fi ojú èyí hàn ni ìlò ìsọdorúkọ tí a ti tọ́ka sí pè ó jẹ́ ọ̀kan nínú fọ́múlà ìṣẹ̀dá fún oríkì ní àwùjọ Yorùbá. Èyí fi hàn pé òwe ni afọ̀ ìpìlẹ̀, oríkì sì ni afọ̀ àfòmọ́ nínú afọ̀ náà. Bákan náà, ó ṣeé ṣe kí oríkì náà jẹ́ afọ̀ ìpìlẹ̀, kí òwe sí jẹ̀ afọ̀ àfòmọ́ nínú rẹ̀. Àpẹẹrẹ irúfẹ́ afọ̀ bẹ́ẹ̀ hàn nínú àyọlò oríkì ìlú Ṣakí ìsàlẹ̀ yìí:

Ọmọ Akínbẹ́kùn
Ọmọ òṣọ́-òru
Ọmọ ọ̀ṣọ́ òru kò yẹni
Àgbàwọ̀ sòkòtò kò yọmọ ènìyàn
Ọmọ àgbàwọ̀ sòkòtò
Bí kò fún wọn lẹ́sẹ̀ yóò ṣò wọ́n
Rẹ́gírẹ́gí lohun tó bá jẹ tẹni
N ba ni lára mu
(Oríkì Ìlú Ṣaki)

Nínú àyọlò oríkì ìlú Ṣakí yìí, òwe tí ó jẹ yọ ni ọ̀ṣọ́ òru kò yẹni, àgbàwọ̀ sòkòtò kò yọmọ ènìyàn. Lára orúkọ ọba Ọkẹ̀rẹ̀ Ṣakí kan tí ń jẹ́ Ọ̀ṣọ́-òru ni wọ́n ti ṣẹ̀dá òwe tí ó jẹ yọ nínú oríkì náà. Ìtumọ̀ òwe náà ni pé kí ènìyàn ṣe ọ̀ṣọ́ níbi tí yóò ti yẹ ènìyàn àtí àsìkò tí yóò yẹ ẹ́, nítorí ọ̀ṣọ́ tí ènìyàn bá ṣe lóru kì í ní ìtumọ̀. Bákan náà, kì í ṣe ohun tí ó dára kí ènìyàn máa yá aṣọ wọ, nítorí pé aṣọ yíyáwọ̀ kì í ṣe déédé ara ẹni tí ó yá a wọ̀.

Àrífàyọ ni pé ọ̀nà kan láti ṣẹ̀dá afọ̀ tàbí fi kún gígùn afọ̀ ni híhun afọ̀ pọ̀, èyí tí ó jẹ́ ìwọ̀núbọ̀nú-afọ̀. Èyí yàtọ̀ sí àyàbá lásán, ó sì yàtọ̀ sí ìyapa, ohun tí ó jẹ mọ́ ni híhun

onírúurú ẹ̀yà afọ̀ pọ̀ gẹ́gẹ́ bí odidi afọ̀ kan ṣoṣo, níbi tí a ó ti rí afọ̀ ìpìlẹ̀ àti afọ̀ afarahẹ, èyí tí ó jẹ́ ọ̀nà kan nínú ìmọ̀ ajẹmẹ́wà àti ìṣọwọ́lò-èdè.

**Ìhásórí Afọ̀**

Ó hàn nínú àlàyé iṣẹ́ yìí ṣáájú pé afọ̀ alohùn ni ó pilẹ̀ gbogbo afọ̀ Yorùbá pátá. Ọ̀kan pàtàkì nínú ohun tí ó sì jẹ́ àbùdá afọ̀ alohùn ni gbígbé afọ̀ sínú ọpọlọ. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí pé ṣaájú kí àṣà mọ̀-ọ́n-kọ̀-mọ̀-ọ́n-kà tó dé àwùjọ Yorùbá ni wọ́n ti ń di èrò-ọkàn wọn sí inú àwọn afọ̀ alohùn wọn, tí wọ́n sì ń gbé e sínú ọpọlọ wọn. Èyí ni pé bí ìṣẹ̀dá ìpohùn bá wáyé láti inú ọpọlọ pẹ̀lú àròjìnlẹ̀, inú ọpọlọ náà ni wọn yóó pa á mọ́ sí, kí ìgbéjáde rẹ̀ tó wáyé lórí ẹnu. Akitiyan àwọn apohùn láti há afọ̀ sórí máa ń hàn nínú ìpohùn Yorùbá. Èyí hàn nínú àyọlò ìsàlẹ̀ yìí:

Èyí tí n bá fẹ́ gbàgbé
Ewe´eean kó máa rán mi létí
Iṣu kì í ta, kó gbàgbé ewé
Àgbàdo kì í yọmọ, kó gbàgbé ìrùkẹ̀rẹ̀
A kì í kọ́lé tá, ká gbàgbé òòlé
Bákùkọ bá kọ, a sì róye

Àyọlò ọfọ̀ òkè yìí fi akitiyan àwọn Yorùbá láti gbé nǹkan sí inú ọpọlọ hàn. Lọ́pọ̀ ìgbà ni irúfẹ́ ìpèdè bẹ́ẹ̀ máa ń jẹ́ lílò pẹ̀lú òògùn ìṣọ̀yè. Bí apohùn kan bá kọ́ ọmọ ìkọ́ṣẹ́ tàbí ẹnìkan ní ẹsẹ afọ̀ kan, dandan kí irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ há ẹsẹ afọ̀ ọ̀hún sí inú ọpọlọ. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń tọ́ka sí afọ̀ alohùn gẹ́gẹ́ bí afọ̀ àtẹnudẹ́nu.

Bákan náà, nígbà tí lítíréṣọ̀ Yorùbá gbòòrò dé ibi kíkọ sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ, gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe ṣàlàyé ṣáájú, ó tún padà gbé àbùdá ìwáyé lítíréṣọ̀ alohùn wọ̀ nípa pé àwọn tí ó ń kọ irúfẹ́ bẹ́ẹ̀ sílẹ̀ tún máa ń padà há ewì tí wọ́n kọ sórí, kí wọ́n sì ké e jáde lórí ẹnu. Ìyàtọ̀ tí ó kàn bá èyí àti ìlànà ìpìlẹ̀ ni pé wọ́n ní àǹfààní láti kọ ohun tí wọ́n fẹ́ sínú ọpọlọ sílẹ̀, bí wọ́n bá sì gbàgbé, inú ìwé tí wọ́n kọ ọ́ sí ni wọn yóó ti lọ tún un kà.

**Ìgbéjáde Afọ̀**

Lẹ́yìn gbogbo akitiyan tí aṣẹ̀dá afọ̀ ṣe lórí ìṣẹ̀dá afọ̀ láti ibi ìṣàwárí afọ̀, àtúntò afọ̀, ìṣọwọ́lò-afọ̀ àti ìhásórí afọ̀, ohun tí ó kàn tí yóò jẹ́´kí àṣeyọrí gbogbo nǹkan wọ̀nyí wá sáyé ni ìgbéjáde afọ̀. Bí aṣẹ̀dá afọ̀ kan bá ṣe gbogbo akitiyan ìṣáájú yìí, láìsí ìgbéjáde afọ̀, 'oyún tí bomubómú bá ní, isó ní fi í só' ni gbogbo akitiyan ìṣẹ̀dá afọ̀ ọ̀hún yóò já sí, bí àlá inú ajá lásán ni. Èyí ní ó fi ṣe pàtàkì pé níbi ìgbéjáde afọ̀ ni aṣeyọrí-afọ̀ wà. Nǹkan méjì ní ó ṣe pàtàkì nípa ìgbéjáde afọ̀. Èyí ni ọ̀nà ìgbéjáde afọ̀ (mode of performance) àti ọ̀gangan-ipò ìgbéjáde afọ̀ (context of performance).

**Ọnà Ìgbéjáde Afọ̀ (Mode of Performance)**

Ọnà ìgbéjáde ni irúfẹ́ ọnà ti aṣẹ̀dá-afọ̀ gbà láti gbé iṣẹ-ọnà rẹ̀ jáde. Àlàyé Ọlátúnjí (1984) fi hàn pé oríṣi ọnà méta ni ìgbéjáde lítíréṣọ̀ alohùn Yorùba lè gbà wáyé. Àwọn ọ̀nà ìgbéléwọn mẹta ti Ọlátúnjí (1984) tọ́ka sí àti irúfẹ́ àwọn afọ̀ tí ó wà lábẹ́ ọkọ̀ọkan wọn ni: Ó ṣe àlàyé pé ewì gẹ́gẹ́ bí ọnà ìgbéjáde kan lè wáyé ni oríṣi ọ̀nà méta tí ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí :


i. Ọ̀rọ̀ geere/ìtàn àròsọ alohùn
ii. Eré-oníṣe alohùn
iii. Ewì alohùn

Ọlátúnjí (1984) tọ́ka sí i pé ewì gẹ́gẹ́ bí ọnà ìgbéjáde kan lè wáyé ni oríṣi ọ̀nà méta tí ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí:

a. Ìṣọ̀kéwì tàbí àrángbọ́
b. ìṣàré

d. orin

Òdìwọ̀n ìgbéléwọ̀n ìpele àti ìgbéṣẹ̀ ọhùn tí apohùn ṣe àmúlò. Àkíyèsí fi hàn pé ó ṣeé ṣe kí ìgbéjáde ẹ̀yà afọ̀ kan ṣoṣo wáyé pẹ̀lú ìgbésẹ̀ ohùn àwọn ọ̀nà mẹ́tẹ̀ẹ̀ta yìí. Èyí ni pé kókó-èrò tí ẹnìkan gbé jáde ni ìlànà Ìsọ̀rọ̀kéwì lè wáyé gẹ́gẹ́ bí ìṣàré, ó sì tún l è jẹ́ gbígbé jáde gẹ́gẹ́ bí orin. A lè lò àtẹ ìṣàlẹ̀ yìí láti ṣe ìgbéjáde lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá.




**Àtẹ: 4**

Gbogbo irúfẹ́ afọ̀ Yorùbá tí ó jẹ́ pé tí ìgbéjáde rẹ̀ bá ti lè wáyé ní ìbámu pẹ̀lú èyíkéyìí nínú àwọn afọ̀ yìí, lítíréṣọ̀ alohùn ni ó jẹ́. Èyí ni ó sì fi hàn pé lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá jẹ́ èkẹ lítíréṣọ̀ tí ó gbòòrò. Abẹ́rẹ́ ìṣọ̀rọ̀kéwì tàbí àrángbọ́ yìí náà ni a lè to ewì ìgbàlódé tí a ṣe àlàyé pé ó jẹ́ ewì àkọ́ké ti wọn ń ké lódé-òní.

**Ọ̀gangan-Ipò Ìgbéjáde Afọ̀ (Context of Performance)**

Ọ̀gangan-ipò ìgbéjáde afọ̀ jẹ́ mọ́ ibi tí afọ̀ alohùn Yorùbá ti wàyé. Èyí ní í ṣe pẹ̀lú ọ̀gangan-ìlò gan-an. Èyí tí ó túmọ̀ sí ibi tí wọ́n ti ń lo lítíréṣọ̀ alohùn tàbí ibi tí wọ́n tì ń ṣe é. Díẹ̀ nínú ọ̀gangan-ipò ìgbéjadé lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ni a fàyọ nínú àtẹ 5 yìí:

| | Lítíréṣọ̀ Alohùn | Ọ̀gangan-Ipò Ìgbéjáde |
|---|---|---|
| 1 | Ẹkún-ìyàwó | Ìbi ayẹyẹ ìgbéyàwó |
| 2 | Ọbitun | Ìbi ayẹyẹ Ìgbéyàwó |
| 3 | Rárà | Ìbi gbogbo ayẹyẹ |
| 4 | Ègè dídá | Ìbi gbogbo ayẹyẹ |
| 5 | Ọ̀ṣàré | Ìbi gbogbo ayẹyẹ |
| 6 | Olele | Ìbi gbogbo ayẹyẹ |
| 7 | Òkú pípè | Ìbi ìṣìnkú |
| 8 | Ìgbálá | Ìbi ìṣìnkú |
| 9 | Ìṣípà ọdẹ | Ojúbọ̀ ògún |

| | | |
|---|---|---|
| 10 | Ìrèmọ̀jé/ìṣípà ọdẹ | Ìbi ìṣìnkú ọdẹ |

**Àtẹ: 5**

**Àwòmọ́ Afọ̀ (Extra text)**

Àwọ̀mọ́ afọ̀ ni àwọn àbùdá lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá tí wọ́n ṣe pàtàkì nínú ìgbéjáde lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, ṣùgbọ́n tí wọ́n kì í ṣá ábà fára hàn gẹ́gẹ́ bí ara afọ̀ tàbí kókó-èrò inú afọ̀. Àwòmọ́ afọ̀ yìí wà lára ohun tí àwọn òǹgbọ́ tàbí àwọn òǹwòran ń wò mọ́ aṣẹ̀dá-afọ̀ lára. Wọ́n sì lè lò ó gẹ́gẹ́ bí òte láti gbé apohùn lé ìwọ̀n. Ìdí nìyí tí ọ̀pẹ́fèyítìmí (2014) fi pé àwọn àwòmọ́ afọ̀ yìí ni àwòmọ́ ìdájọ́. Èyí ni àwòmọ́ ti wọ́n ń wò láti ṣe ìdájọ́ apohùn. Èyí fi hàn pé kí ìṣẹ̀dá afọ̀ dára láti ibi àrògún títí dé orí ìgbéjáde afọ̀, bí àwọn àwòmọ́ afọ̀ wọ̀nyí kò bá kógo já, apohùn le má gba iyì tí ó tó lójú àwọn òǹgbọ́ tàbí òǹwòran.

Lára àwọn àwòmọ́ afọ̀ tí àṣẹ̀dá afọ̀ gbọ́dọ̀ dì mẹ́rù nínú ìgbéjáde afọ̀ alohùn Yorùbá ni ohùn, èdè, ìmúra, ijó jíjó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ọ̀rọ̀ nípa ohùn jẹ ohun tí ó jẹ́ lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá lógún. Fún ìdí èyí, apohùn tí ó bá ni ohùn dídùn, tí ó sì fi ohùn dídùn gbé afọ̀ rẹ̀ jáde máa ń gba àgbàkún iyì lọ́dọ̀ àwọn òǹgbọ́ tàbí òǹwòran. Bákan náà, ìmúra apohùn gbọ́dọ̀ jọjú ní gbèsè, kí ó múra dáadáa lọ sí òde ìṣèré. Yàtọ̀ sí èyí, bí ó bá jẹ́ ìpohùn tí ó la ijó jíjó àti tìlù-tìfọn lọ, apohùn gbọ́dọ̀ mọ ẹsẹ̀ ijó gbé, kí ó sì mọ ọwọ́ ọ́ ijó yọ.

Gbogbo àwọn nǹkan wọ̀nyí jẹ́ ohun tí aṣẹ̀dá afọ̀ nílò gẹ́gẹ́ bí àfikún èròjà fún ìgbéjáde afọ̀ rẹ̀, kí afọ̀ náà lè baà gba iyì tí ó tọ́. Nítorí pé àwọn apohùn Yorùbá mọ pàtàkì àwọn nǹkan wọ̀nyí, ọ̀pọ̀ nínú wọn máa ń jẹ́ àwọn orúkọ tí ó ṣo wọ́n pọ̀ mọ́ àwọn àwòmọ́ afọ̀ wọ̀nyí. Lára irúfẹ́ àwọn apohùn bẹ́ẹ̀ àti àwòmọ́ afọ̀ tí wọ́n so ara wọn mọ́ ni ó wà nínú àtẹ ìsàlẹ̀ yìí :

| | **Apohùn** | **Àwòmọ́ Afọ̀** | **Àbùdá tí ó gbé yọ** |
|---|---|---|---|
| 1 | Ajóbíewé | Ijó jíjó | O fi hàn gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ́ ni ẹ̀bùn àbùda ijo jíjó |
| 2 | Onígba ohùn lọ́nà-ọ̀fun | Ohùn | Ó fi hàn pé apohùn náà ní ẹ̀bùn lílo onírúurú ohùn láti gbé ọ̀kan-ò-jọ̀kan ipohùn jáde |
| 3 | Olóhùn Iyọ̀ | Ohùn | O fi hàn pé apohùn ni ohùn dídùn. |
| 4 | Dásọ̀fúnjó | Ìmúra àti ijó jíjó | O fi hàn pé apohùn ni aṣọ tí ó dára, ó sì tún mọ́ ijóo jó. |
| 5 | Aláwìídùn orin | Ohun | O fi hàn pé apohùn ni ohùn dídùn. |
| 6. | Agbólóhùn bí Ọ̀jẹ̀ | Ohun | O fi hàn pé apohùn ni ohùn tí ó gbó já gaara. |

**Àtẹ: 6**

Àwọn apohùn mọ̀ pé jíjuwe irúfẹ́ àwọn àbùdá wọ̀nyí gẹ́gẹ́ bí ohun tí àwọn ní yóò fi kún ìwárapàpà àwọn òǹgbọ́ tàbí òǹwòran láti fẹ́ gbọ́ tàbí wo ìṣèré àwọn.

**Àgbálọgbábọ̀**

Ìṣẹ́ yìí ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ohun tí ó jẹ mọ́ àbùdá ìṣẹ̀dá afọ̀ ajẹmọ́-lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, ó sí tún wo àwọn ohun tí ó jẹ́ onímọ̀ ìpohùn. Èròńgbà ṣíṣe èyí ni láti gbé ìlànà kan kalẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ìlànà tí yóò ṣeé múlò láti ṣe ìtúpalẹ̀ ìṣẹ̀dá àti ìgbéjádé àwọn lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá. Ìgbéṣẹ̀ ìṣẹ̀dá lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá àwọn tí iṣẹ́ yií fi hànde ní ìwárí tàbí àrògún (èyí tí ó jẹ mọ́ ìṣàmúlò èrò, ìrírí, ìsípayá), àtúntò afọ̀, ìṣọ́wọ́lò afọ̀, ìhásórí afọ̀ àti ìgbéjáde afọ̀ (èyí tí ó jẹ́ ọnà ìgbéjáde afọ̀ àti ọ̀gangan-ipò ìgbéjáde). Bákan náà, àwọn àwòmọ́ afọ̀ tí iṣẹ́ yìí ṣe afihàn ni ohùn, èdè, ìmúra àti ijó jíjó. Iṣẹ́ yìí jẹ kí ó hàn pé nígbà tí ó jẹ́ pé láti bí ìṣàwárí afọ̀ àti àrògún ni ìṣẹ̀dá lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ti wáyé, àwọn nǹkan yìí

náà nì ó sì ṣe pàtàkì láti ṣe ìgbéléwọ̀n apohùn àti ìpohùn rẹ̀. Èyí yóò sì jẹ́ ìlànà ìtúpalẹ̀ ṣe wẹ́kú pẹ̀lú ìlànà tí lítíréṣọ̀ gbà wáyé.

**Ìwé Ìtọ́kasí**


Abímbọ́lá, W. (1967). *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá: Apá kìíní.* Glasgow: Collins

Adémúyìwá, A. L. (2017) "Ìtúpalẹ Ìṣọwọ́lò-Èdè Nínú Àṣàyàn Ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù". M.A. Thesis, Department of Linguistics and African Languages. Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University. Ilé-Ifẹ̀.

Adémùyíwá, A. L. (2022). "A Critical Analysis of Thematic and Stylistic Features in Oríkì of Towns in Òkè-Ògùn". Unpublished Ph.D. Thesis, Department of Linguistics and African Languages. Ọbáfẹ́mi Awólówọ̀ University, Ilé-Ifè.

Adépọ̀jù, O. (1972). *Ìrònú Akéwì.* Ìbàdàn: Onibonoje Press & Book Industries.

Akìwọwọ, O. (1986). *Àsùwàdà-ènìyàn nínú Àjùwọ̀n*, B. (ed) Ifẹ Annals of Cultural Institute, Obafemi Awolowo University Press, Ile-Ife.

Ajíbádé, G.O. àti Rájí S.M. (2011). *Ewì Àlàbí Ògúndépò.* Ìbàdàn: Alafas Nigeria Company.

Ajuwọn, J.A. (2013). '*Àrọ̀: Ipèníjà tó fẹjú' LAANGBASA*: Jọ́nà Iṣẹ́ Akadá ni Èdè Yorùbá. No. 17. University of Lagos. Pp. 96-106

Bamgbose, A. (1967). 'The form of Yorùbá Proverbs' Odù: *Journal of Yorùbá and Related Studies,* 3, 9-26.

Burke, M. (2013). "*Rhetoric and Poets:* The classic heritage of stylistics" Ninu Burke, M (ed) The Routledge Handbook of stylistics. New York: Routledge.

Iṣọla, A. (1978). *Àfàìmọ̀ àti àwọn Àròfọ̀ Míràn*. Ìbàdàn: University Press Limited.

Jamil, M.B. and Yang, Y. (2012). A Case Study of the Novel, Siddhartha from the Perspective of Intertexuality. *Journal of Education and Practice*. Vol.3, no. 14. Pp. 141-147

Olasebikan, A.I. (2023). *Ojú Àmúwayé Yorùbá nínú Àsàyàn Òwe Ajẹmọ́-Aìsàn àti Ipèníjà ara ni Àwùjọ Yorùba.* (An Appraisal of Yorùbá worldview on Sickness and disabilities in Selected Yorùbá Proverbs). Unpublished M.A Thesis, Department of Linguistics and African Languages, Obafemi Awolowo University, Ile-Ife.

Ọlátúnjí Ọ. (1982a). *Ewì Adébáyọ̀ Fálétí Ìwé Kínní*. Ibadan: Heinemann Educational Books (Nig.) Limited.

Ọlátúnjí, Ọ́. (1982b). "*Classification of Yorùbá Oral Poetry*" Afọ́láyan, A (ed). Yorùbá Language and Literature. Pp. 57-81.

Ọlátúnjí, O. O. (1984). *Features of Yorùbá Oral Poetry*. Ìbàdàn: University Press Ltd.

Ológundúdú, K. (2009). *Adé Orí Ọ̀kín: Àṣàyàn Ewì Oríkì, pẹ̀lú Àlàyé Lẹ́kùn-ún rẹ́rẹ́.* Ìbàdàn: Penthouse Publications (Nig.).

Ọ̀pádọ̀tun, O. (2003). *Òǹkọwe àti Ìwé Kíkọ Alátínudá.* Oyo. Odumatt Publishers.

Recebido em: 23/02/2025

Aceito em: 24/06/2025

**Para citar este texto (ABNT):** ADEMUYIWA, Adewale Lukman. Ọgbọ́n ìṣẹ̀dá àti àwòmọ́ afọ̀: ìlànà fún ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), vol.5, nº Especial I, p. 140-153, jan./jun.2025.

**Para citar este texto (APA):** Ademuyiwa, Adewale Lukman (jan./jun.2025). Ọgbọ́n ìṣẹ̀dá àti àwòmọ́ afọ̀: ìlànà fún ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), 5 (Especial I): 140-153.